# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 533 LAGOS SATURDAY AUGUST 18. — AUGUST 24, 1962 KOBỌMEJI (2D)


NITORI OWO TI KO LO DEDE

# Oyinbo Kan Gbe Sende Je

LONDON—Oyinbo oni gẹdu kan ti orukọ rẹ njẹ Herbert Leman ti o ti nṣe owo gẹdu ni ilẹ enia dudu ri ni a gbọ irohin wipe o gbe sendẹ jẹ, o si pa ara rẹ nitori adanu ti o pa lori isẹ gẹdu na ti o nṣe.

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ Oyinbo onigẹdu na ni pe ni nwọn nkan bi ọdun mẹjọ Leman, eni ọdun meji-dinladọta, ba iṣẹ gẹdu wa si Ipinlẹ Iwo orun Nigeria, sugbọn larin ọdun 1957 ati 1959 ni nkan beresi lọ silẹ fun un. O pada si ilu Oyinbo, o wa awọn ojulumọ, o fa won mọra nwọn tun ba wa owo kun owo ti o wa lọwọ rẹ o pada si Nigeria.

Gbara ti o ti tun de Nigeria o tun bẹresi ra igi gẹdu lọtun losi; gbogbo awọn ti o ra na o ko nwọn ranṣẹ si ilu Oyinbo sugbọn nigbati nwọn wa awọn gẹdu na gunlẹ nwọn ri wipe gbogbo rẹ ni awọn kokoro "jẹjẹrẹ" ti jẹ bajẹ. Eyi jẹ ki o padanu papọ, o si ba ara jẹ kọja.

Nigbati o pada si ilu Oyinbo, o pe awọn ti t'on pẹlu wọn jọ da isẹ lu lẹjọ, o si jẹbi. Eleyi jẹ ki o ro gbogbo rẹ pin, o si ra sẹndẹ, o gbe e jẹ, o ni aiye su on.

---

## Owo Olopa Te Toko-taya Ti Nro Owo

Ọwọ awọn Ọlọpa tẹ tọkọ taya ti nwọn njẹ George Nwokolo Okwesa eni ọdun metadinilogorin ati iyawo rẹ Helina, ẹni ọgọta ọdun, nib'ti nwọn gbe ti nrọ owo

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


Advt. NO. 109

## IKEDE

OWO ATIJỌ TI WEST AFRICAN CURRENCY BOARD

Lati ọjọ kini oṣu July, 1962, eyiti iṣe oṣu keje ọdun yi, gbogbo owo atijọ patapata ni pepa kọrẹnsi ati ṣile pẹlu owo wẹwẹ miran bẹ ti West African Currency Board ti kuro labẹ ofin ni jake jado ilẹ Nigeria. Owo yi ko ni ṣe na mọ fun sisan gbese tabi ki o wulo fun tita tabi rira ọja ni sọọbu ati ni ọja. Ṣugbọn owo wọnyi ṣi ni iye lori ati wipe ẹnyin si le ṣe paṣi-parọ wọn ni gbogbo Bank.

Lati ran yin lọwọ, Central Bank ti Nigeria ti ṣe eto pẹlu gbogbo Bank pe ki wọn ma ṣe dẹkun lati ma ṣe paṣi-paro owo pepa kọrẹnsi ti atijọ l'ofẹ fun awọn enia titi di ipari oṣu September, 1962, ti nṣe oṣu kẹsan ọdun yi ati fun owo ṣile ati awọn isọngbe rẹ titi di pari oṣu December, ti nṣe ipari ọdun yi.

Nitorina a bẹ gbogbo yin patapata lati mu owo atijọ ti o mbẹ lọwọ yin lọ si Bank ti o ba sun mọ yin ki Ẹ lo ṣe paṣi-paro won l'ofẹ si owo Nigeria titun ti Central Bank fi si ode ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Ẹ ma ṣe jaf'ara.

Gbogbo ẹniti ko ba parọ owo atijọ ọwọ rẹ si owo Nigeria titun titi asiko ti a fi silẹ fun yin ba fi pari yio san owo fun Bank nigbati o ba fẹ ṣe pasiparọ owo atijọ rẹ lẹhin ọjọ wọn yi.

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
LAGOS.

**W. A. TIBBLES**
GENERAL MANAGER



## LAGOS RACE CLUB

Last Day
August Race Meeting
TODAY
First Race at 3.15 p.m.

**Come One Come All.**

Hon. Secretary,
Lagos Race Club.

# Awo Irawo

## E yi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Bi gbogbo irawọ rẹ ti yọ si ninu ọsẹ yi, gbogbo nkan a da fun ọ ṣugbọn ki o ṣora pẹlu ọrọ kekere ti ko to nkan ti wa fẹ mọ ba wọn jiyan si

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ninu ọsẹ yi o ko ni fẹ doju kọ iṣẹ rẹ tara; gbogbo rẹ a ma ṣe ọ tikọ tikọ. Ṣọra pẹlu ... ti o ba ... ki o moṣe fi i ... rẹ.

ARIES (Mar 21-April 20) Iwọ fẹ nrẹ rẹ ni wa ṣe olugbala ara rẹ ninu ọsẹ ti a bọ si yi; ko si nkankan ti ... de ba ọ ti o ko ni ni agbara lati gbidanwo lati ṣe funra rẹ. Ọjọ ... je (Monday) ni ọjọ irawọ ti o dara fun ọ.

TAURUS (April 21-May 20) Irawọ rere wa fun ọ ni ọjọ ... je ati lọjọ keji rẹ (Monday ati Tuesday) ṣibẹ-ṣibẹ nkankan a ru ẹ loju ninu ọsẹ yi. Wa gbunṣ irohin rere kan lati ọdọ awọn ẹbi rẹ.

GEMINI (May 21-June 21) Ọrọ tirẹ dara, ṣugbọn maṣe ti itori yen k ... o yọ ayọ ayọ ọrọ. Wa ba ẹre ti yio tan ẹ lọwọ pade.

CANCER (Jun 22-July 23) Awọn enia pataki yio ri si iṣẹ owo rẹ. Gbidanwo lati tẹ siwaju ninu ohun gbogbo ti o nṣe.

LEO (July 24-Aug 22) Gbidanwo lati foju fo awọn nkan ti ko to nkan ti awọn kan a fẹ jẹ ki o bi ọ ... ninu larin ọsẹ yi, ṣugbọn ki o mọ wipe lọjọ Monday ati Wednesday irawọ rere yo fun ọ.

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Ọsẹ yi ki ṣe ọsẹ idera ninu ki nwọn pe ọ si ... ti ko ni lari kan— maṣe ba wọn lọ. Wa ri irohin kan gbọ lati ọdọ olufẹ rẹ.

LIBRY (Sep 24-Oct 23) Maṣe kọ ... ọrẹ lori nkankan, ṣugbọn ki o ṣora lori ọrọ ife.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) ... awọn ojulumọ ti o gbọ tirẹ sere ninu ọsẹ yi. Ma ya ẹnikan lowo rara ... wa ... an.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Wa gbọ irohin ... kan ti yio fẹ ba ọ ninu jẹ. Maṣe ba ara jẹ.

CAPRISCORN (Dec 23– ... n 21) Ọrọ ... ni yio gba ọpọlọpọ asiko rẹ— jọwọ maṣe ba ẹnikẹni jiyan lori ọrọ kan rara.

# Ogbeni Ibiteye Se Ajodun Isu Egbodo

MUSHIN— Laipe yi ni Ọgbẹni P.S. Ibitẹyẹ ṣe ajọdun iṣu egbodo ni Oke Arin, Ilupesi, Mushin, gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ ilu rẹ ati bi baba rẹ ologbe Oloye S. Ọnhọ ni ilu Ogidi Ijumu ti i maṣe. Gbogbo awọn ẹbi ati ọrẹ ni o pe si ibi ajọdun na pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ Ifẹloju ọmọ Ogidi Ijimu. Ọgbẹni Ibitẹyẹ si fi nkan jijẹ ati mimu tẹ gbogbo wọn lọrun.

Diẹ ninu awọn ti o wa si ibi ajọdun na ni Ọgbẹni S. O Ọbaniyi, S. A Danọlẹkun, J. A. Adeyẹmi, E. Bada, J. Agbo..., S. Bekaye, S. Adeyemi, Balogun Ọbagowo, J. A. Dawodu, J. Aluko, S. A. Agoro, J. Ọmọjọla, J. Adeyanju Ajetunmobi Charles, Iya'fin Christie O. Edu, Alice A. Adeogun, Ọlayemi Ọbatolu, O. Fọlakẹ, A. O. Alice, E. A. Ajọkẹ, C. Ariyikẹ, Iyabeji, Morẹnikẹ, A. C. Abiodun Ibitẹyẹ, J. Ọlayemi Ọbatolu, Y. Ọbatolu, Dawudu, Morẹnikẹ ati O. Ajayi.

Awọn ti ko le wa ti nwọn fi iwe ki eni ajọdun na ku ọdun ni awọn bi Minisita S. A. Ajayi, Alufa D. I. J. Oladugba, S. T Ibitẹyẹ, J. M. Ọladuọu, S. A. Abiọla, S. O. Alafiatayọ ati Iyafin Fọlakẹ Ajayi.

# Egbe Iwalewa Ndabira

EBUTE METTA— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn Ẹgbẹ Iwalẹwa ṣe ipade alarinrin kan ni ọdọ Iya-afin Ọlayinka Apesin ni Jẹbba Street, l'Ebute Mẹtta. Iya-afin yi ni ẹniti o kọkọ ṣe adura fun gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Iwalẹwa yi nigbati ipade na bẹrẹ.

Ọgbẹni E. O. Akinwande ni o dele de alaga, Ọgbẹni S. B. Emanuel ti ko le wa si ibi ipade ọjọ na-o si kesi igbakeji alaga, Ọgbẹni J. A. Ajala ki o ba awọn ọmọ ẹgbẹ na sọrọ ipa ilọsiwaju ẹgbẹ na ati bi ijoko ẹgbẹ na ti ri. Baba Isalẹ Ẹgbẹ na Ọgbẹni S. A. Subẹru, si ba gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ na sọrọ iṣiri lẹrisirisi gbogbo awọn ẹgbẹ si fun ti Baba Isalẹ na ni adura kikun.

Gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Ifẹlodun lo pe sibẹ siba siba, awọn si fi nkan jijẹ ati nkan mimu tẹ wọn lọrun. Diẹ ninu awọn ti o wa si ibi ipade ajọyọ na ni Ọgbẹni G. A. Odufuwa, E. O. Sasọgbọn, A. A. Adepitan, V. Ọlọta, J. A Lawal, Thomas Alikama, S. O. Ajala, E. Ade. Mann, S. Shonubi, J. A. Adekoya, A. O. Ajala, Lasisi Alade, Y. A. Balogun, R. Sotayọ, M. A. Sonẹyẹ, I. Adegbitẹ, M. J. Ọlọta, S. Bọlaji Haroun, M. Afọlabi, Ade. Emanuel ati M. I. Elegbede.

# Oba Lola



Eleyi ni aworan ti Ọmọ Ọba ilu Oyinbo, Charles ti nwọn npe adape orukọ rẹ ni Ọmọ Ọba ilu Wale ṣẹṣẹ gba laipẹ yi

"OMO OBANTA" NI ORO YI

# Kise Gedegbe L'Eko Wa Mo

…won Yor…ba ni oro gbogbo lo…i ala… Ijapa. E…ni omo Obanta ti mo nko iwe yi ti wa…ri gbangba wipe nigba…ugba ti ruke-rudo kan ba bo sile ni ile Nigeria, awon omo Ijebu ni lati je enikan ti nwon ni lati na dareko won si ona buruku nibe.

## Rikisi Ko Dara

Emi ko mo nkan ti o faa, sugbon mo ri wipe a feran oro abosi, ki'a mo je ara walese. Ko si ilu ti abosi ko si sugbon ti awon Ijebu ni o peleke.

Nigbati mo lo si ilu Oke ni enu l o l o y i oju 'mi ri opolopo kan, eti mi si gbo orisirisi oro. Ti a w o n Hausa ni o fe gbo ni tabi ti awon Ibo; ti awon Ogbomosho wa loto. Ogbomosho ni opolopo awon enia npe mi ni gbogbo ibiti mo lo kakari. Mo de Kaduna lati Zaria.

Lati Bukuru ni mo ti gba de Jos (Kasa Nkusa). Lehin Kano, mo tun fe mo ilu ti o ni yi ni Ipinle Ijoba Ariwa. Ko si mo. Kaduna ni oruko lasan ni ko ni iyi rara bi ti Kano. Ilu Kano yi ni gbogbo awon oko aropileni nla nla ngba. O si je ibi pataki fun ise owo sise.

Oro Oba Kano p e l u awon omo egbe NPC (egbe Sardauna) ti daru nisisiyi. Sibesibe awon Hausa ko fi ara won sile. Nwon di ara won mu sinsin.

Gbogbo awon o m o ti nwon ko mo iwe tobe ni nwon ti wa ise fun nibi pataki p a t a k i ni ile ise Ijoba. Bi o ba de Zaria ti o ri ibiti nwon ti nko awon omobinrin won leko nisisiyi enu yio ya o. Gbogbo awon omo Hausa nwonyi ni nwon nfi si enu ise lemolemo.

Laipe yi ni Olola Sardauna tun lo ba awon omolewe ti o sese fe jade ilewe giga ilu Sokoto soro pe ki nwon te siwaju ninu eko won nitoripe eniti ko ba ja fafa ninu eko re awon ki yio gba sinu ise Ijoba nibikibi mo.

Gege bi mo ti so ni ako… …ko wipe awa Ijebu feran tembelekun pupo; awa na ni a se "balogun" ti nwon fi fo egbe oselu kan ti awon odo kan da sile nigbakan, ti nwon so oruko re ni Nigerian Youth Movement.

## Gedegbe

…egbe Youth Movement yi se bobe lori oro ilu Nigeria nigba na. Oro ile iwe-giga Igbobi (Igbobi College) ti awon Ijoba igba na fe se baku-baku, awon omo egbe yi ni o tete toka si ona aise dede ti o wa nipa ile-iwe na. Ijoba igba na si tun un se.

Awon omo egbe na ni o je ki oju gbogbo ara ilu Nigeria ja si oro idibo (Election), awon na si se nkan ribiribi lori ibodidi na ni ilu Eko ninu odun 1938.

## L'Eko Wa

Kise wipe awon ti pa itan fun mi, awa Ijebu yi ni a ko se "seriki" olorin, ti a beresi ko orin "gedegbe l'Eko wa" ti a se rikisi titi ti nwon fi yo ilu Eko kuro lara awon ilu Yoruba yoku. Kinni ere ti a ri gba ninu gbogbo tembelekun yi? A ko ri ibukun kan nibe, a ti abuku.

L'ose ti mbo "OMO LISABI" lati ilu Egba l'Abeokuta a ko…we tire nipa bi nkan ti nlo si ni NIGERIA ninu asiko ti a wa yi.

## Ikilo Tuntun

…ko ba mo ibiti a nlo, a …o ibiti a ti mbo. M o f e s e ikilo kekere fun gbogbo a w a om… Ijebu wipe ki nwon jowo, ki nwon je ki a se pele-pele nipa rogbodiyan ti o wa ni Ipinle I j o b a I w o orun nisisiyi. Ki a mase se ni " ona ofun, ona o r u n " gegebi oro Ayiluka Eleti-ofe.

Oro nla nbe o, Obanta yio g b o gbogbo wa lokunrin ati lobinrin.

## Ijoba Ghana Le Alufa Ojise Olorun Kuro Nilu

GHANA—I j o b a ilu Aganyin (Ghana Govt.) ti Dokita Kwami Nkrumah nse Olotu won l e Alufa agba ojise Olorun kan ti nwon npe ni Rev. Richard Roosevare. Bisobu I j o C. M. S. ni Accra j a d e kuro ni i l u nitori iwasu kan ti o wa fun i j o sosi re laipe yi lori egbe awon omo kekere ti Ijoba i l e na nko l'eko ti o lodi si ona Olorun.

Kakiri gbogbo ile Ghana awon omo egbe o s e l u Dokita Nkrumah ti nwon npe ni Convention Peoples' Party ( C P P ) da e g b e kan sile fun awon o m o keke ilu na, nwon si npe w o n ni Young Pioneers. Eko jagunjagun ati pe ko si Olorun kan ni ibikan ni nwon nko won.

Bisobu yi ninu iwasu r… ni orin alufasa a t i e k o bubur… yi ko le se nkan rere kan fun a w o n omo wonyi Ijoba ola. Oro iwasu yi lo … si ori awon olotu Ijoba ghana, nwon si ni ki ojise Olorun na fun awon laye nilu won.

## Oke Mewa Ponun Ni Ijoba Padanu Lori Iwe Irohin

EKO—… onipako n… … ara … lo n r… …, ni oro awon olotu I j o b a … (Federal Government) l'Eko ti nwon da awon egbe … iwe irohin kan sile ninu odun ti o koja ti nwon npe ni Nigerian National Press ti nwon nte i w e irohin "Morning P o s t" ati "Sunday Post" ni Apapa; ni aarin odun kan ti nwon bere i si te awon iwe irohin na, oke mewa ponun (£200,000) sarai ni nwon ti padanu lori awon iwe tite won na.

Alamojuto iwe owo-nina Ijoba (Auditor) ti o lo ye iwe won wo n i ( b i ) nwon ti se nna owo at pe iwe owo-nina ti nwon nko sile

(Wo yoku loju ewe kefa)

PHILIPS
for RADIO
PHILIPS

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos. P. O. Box 468

CABLES & TELEGRAM "ELETI ỌFẸ," LAGOS Phone 23370.

VOL. XIV. No. 833. SATURDAY AUGUST 18,-AUGUST 24, 1962


# Lehin Irun Kiki

NINU ọsẹ ti a wa yi ni gbogbo awọn Imale jake-jado gbogbo ilẹ Nigeria ṣe iranti ọjọ'bi Anabi Mohamed (ise ati ọla ki o ma ba a), o si yẹ ki a ki oganiọgọ awọn ọlawe wa ti o jẹ ẹlesin Imale ku ọdun ọjọ'bi na, ṣugbọn nkankan ba ehin aja jẹ – iyẹn ni otitọ ọrọ ti ko fi gun awọn ẹlẹsin Imale ti Nigeria yi lara ninu ọrọ Oloru ti ọsẹ yi.

Nitotọ a gba fun ẹnyin obi ti ẹ wọ aṣọ otiṣiṣisi fun ọmọ nyin, ti ẹnyin na si di gele mo'ri, ti ẹ mu tẹsuba yin, ti ẹ si kirun kurakura. A gbọ wipe ẹ pe na, iwa yin nkọ?

## Adura Lo'ku

Loni, aṣa'aṣa lọwọ awọn ọmọ Imale ni o pọ si. Bi olorọ nṣe ọdun ọro awọn ni wa ba nibẹ. Bi elegungun nṣe odun egun, Wosilatu ni yio ṣe iya ajin, Lamdi ni yio ṣe atokun ni igbalẹ.

Bi o ba ni ọga ti ko jẹ ki o simmi nibi iṣẹ tabi iya'le ti ko jẹki ọkọ gbọ tire, ọrọ ati doju wọn kọ orun alẹ ko soro ti o ba tọ ni baba Alufa a-tẹ-tasi ni kọrọ. Ọpọlọpọ awọn ọlọṣa lobirin ati lọkunrin ni awọn baba Alufa yi fi di igbo fun, ti nwọn si ti sọ ọpọlọpọ ile di ahoro.

Ṣe iru iwa bayi ni Anabi na kọ yin ninu iwe Alukorani ? Ara, ẹ kiyes'ara.

Lẹhin irun kiki adura ni o ku, ki ẹ tọrọ idariji, ki ẹ ye ba tomọ ọlọmọ jẹ. Iyẹn ni ọna rere ti Alukurani kọ wa.

# Kitoyi, Ghana ?

Irohin kan ti a gbọ lati ilu Ghana ninu ọsẹ yi, wipe awọn Olotu Ijọba ilu na le Alufa ojiṣẹ Ọlọrun, Enịọwọ Bishọp Ijọ C. M. S. kan kuro ni ilu wọn nitori iwasu ti o se lọjọ ọsẹ kan ninu Ṣọsi wipe ki awọn obi ko ṣe ikilọ fun awọn ọmọ wọn nitori ẹgbẹ YOUNG PIONEERS ti awọn oṣelu na da silẹ fun ọmọ lẹkọrẹ, ti awọn si nkọ wọn ni ọna ti o lodi si ọna Ọlọrun.

Otitọ ọrọ bi iṣọkuṣọ ni o nri, ṣugbọn awa oniwe irohin Eleti-ọfẹ gba fun Ẹnịọwọ Alufa Roseveare ti o roju sọ oju abẹ ni iko. A fẹ ki awọn Olotu Ijọba Aganyin (Ghana) yi ranti pe "Afẹ ti o gbọn jaṣa ẹbiti ti pa". Hitler ṣe ju bayi lọ si awọn ojiṣẹ ọlọrun ni ilu Jamani (Germany). On na da lode nai ?

# Iwe Si Olotu

## Awo Irawo Nyin Dara Pupo

Olotu,

Mo gba fun Ọgbẹni ti o awo irawọ fun yin ti ẹ nte sinu iwe irohin Eleti-Ọfẹ fun wa Lọsọsẹ. Mo gbadun asọtẹlẹ tire ju ti awọn elomiran lọ.

O to igba kerin nisisiyi ti mo ti nṣe akiyesi asọtẹlẹ nkan ti o wi nipa temi, ti o si nṣẹ bẹ ẹ.

Ninu ọsẹ ti o sọ wipe mo ni lati n'awo anuradi, mo gbin-danwo ki nmi na a ṣugbọn nkan ẹbi kan kan mi ti mo ni lati n wo pupọ nibẹ.

Ni ọsẹ ti o si ma ma irin-ajo kan nitotọ mo lọ ni ilano tele.

Bẹna ni ọsẹ ti o sọ wipe ma ri iwe kan gba lati ilu Okere. E jọwọ, ẹ ma ba wa sọ fun awo irawọ na ki o ma ba wa ṣe asọtẹlẹ na siwaju si.

Emi ni,
Jacob Adelu

Shomolu

## E Tete Ba Wa Se Oju Ona Olomu

O ti pẹ ti awọn Igbimọ ibile Ifẹ ti ngbero lati ṣe oju ọna mọto lati Ifẹ lọ si Olomu ni agbegbe Abẹokuta ṣugbọn titi di oje oni a ko mọ bi nwọn ti ṣe gba wọn lori ẹrọoju ọna na si.

A gbọ nigba kan wipe nwọn tiṣe ẹto oju ọna na tan ki rogbodiyan to de ba Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni ko jẹ ki nwọn ti yanju ọrọ oju-titi na. E jọwọ ẹ ba wa kesi awọn igbimọ ibilẹ ni Ifẹ ki nwọn jọwọ ki nwọn tete ba wa yanju ọrọ oju ọna mọto na ki a le ma ri ọna gba ko ọnẹ wọlu.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi. Olotu, Ọlọrun yio mọ pelu yin ati alabaṣiṣẹpọ yin.

Emi ni,
Ifẹ.                Olayide.

## E Ma Fi Eleti-Ofe Sowo Si Wa

Laipẹ yi ni mo wa ki ọrẹ mi ni Eko ti mo si ri iwe irohin nyin, Eleti-ọfẹ ni ọdọ ọrẹ mi na. Mo bi lere bi lọsọsẹ ni iwe irohin na tun njade bi ti atijọ, o ni bẹni.

Nigbati ẹniti ti nlọ si ile iwe ni iwọn bi ọdun marundinlogoji ni emi ti nma ra iwe yi fun ẹgbọn mi ti mo si nṣina ka a lọdọ rẹ.

Inu wa yio dun bi ẹ ba le wa aṣoju kan si ibi ti yio ma ta a fun wa.

Emi ni,
A. Atanda
Iboro
Leti Abẹokuta.

## ỌRỌ OLOTU.

Nigbati Hitler Ologun Jamani (Germany) yi kọ bẹrẹ ọdọ awọn ọmọde ilu ni o kọ bẹrẹ, ti awọn Ojiṣẹ Ọlọrun bẹrẹ kilọ fun un, ṣugbọn ko gbọ nṣe ni o nle awọn Alufa yi jade ti nwọn si npa wọn.

Ki a pa ti awada ti, awa na ri wipe iwa ori-kikun, aibọwọ fun agbalagba, aibẹru Ọlọrun ati orin alufaṣa ti nwọn fi nkọ awọn ọmọ yi ko le ṣe wọn lohun rere lẹhin ọla, a fi ọna iparun lati ma wa nkan ti ao fi pa ara ilu lara kiri.

Kinni o nda awọn ilu alagbara bi Russia lamu kiri lọjọ oni ti nwọn ko le san, ti nwọn ko le wo? Aini iberu Ọlọrun lọkan ni. Bẹ "iberu Ọlọrun ni ipinlẹsẹ ọgbọn".

Ẹnyin ara ilu Ghana, kinni ẹ mọ eyi si ?

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Eni–nla Ni ...

Irohin ti o gbo gbogbo awọn ara Eko jigijigi ni ọsẹ ti o kọja yi ni ti awọn Oloye marun ti a gbọ wipe Ọba Adele ni on rọ wọn loye, nwọn kiṣe Oloye on mọ; nitorina bi "ọbẹ adidun" ti awọn nkona mọ ba ti delẹ, ki awọn oloye yi maṣe na'ga si apa ibẹ rara.

Ẹni-nla ni nṣe nkan nla, Adele ọmọ Buramọ, ọlọgbọn ti di ori ẹja mu! Mo gbọ wipe awọn Oloye rẹ yi paapa ti gbọn nisisiyi awọn na ti so'wọ pọ, nwọn ti di arin ẹja oni guta mu ṣinṣin.

## Se Nkan Nla

Awọn Oloye na ni awọn alaimọkan enia ni o fẹran ori ẹja ni jijẹ, awọn Oyinbo ki jẹ e. Ọrọ wa di ọrọ awọn ọlọgbọn meji ti o pade ara wọn. Mo gbọ wipe Oloye Aminu Kosọkọ, Asajọn Ereko ni ATỌBATẸLẸ ni awọn. Ọrọ kiṣe ọrọ ọbẹ tutu adimu wa ntọ ọ la, awọn alara ni awọn tilẹ siṣe ọbẹ na sibẹ.

Emi Ayiluka gbọ wipe bi aṣa iṣẹdalẹ ilẹ Yoruba, Oloye kan ko ni ẹtọ lati yọ awọn Oloye ẹgbẹ rẹ l'ẹgbẹ, ṣugbọn aiye atijọ niyen aiye ti di aiye Sarudauna tabi ti Tarfawa ni ki a pe e?

Ẹ wa gbọ o! ki a fi suru si ọrọ na, ki a mọ sọ di ọrọ ọtẹ nitoripe mo gbọ wipe awọn kan ninu awọn ẹbi oloye ti awọn sọ wipe awọn rọ loye yi ti ndu awọn oyẹ na ni Iga Idunganran, ọpọlọpọ awọn enia ni nwọn si ti nlọ ra igan aṣọ olowonyẹ ni ṣọbu Oyinbo Ọlọwọ ni Ẹhingbẹti, ti nwọn yio fi ran fila oye ati aṣọ idabora.

Eleyi ara! iyẹn ni pe bi t'enia kan ko ba bajẹ ti enia kan ko ni sunan? Ki a si mọ wo o na; emi Ayiluka paapa ko ti kuro lẹhin Iga.

## O Nje Tirebo....

Mo gbọ wipe awọn Oyinbo onisowo kan ti nwọn nṣe iṣẹ a-da-yi-dun fẹ bẹrẹsi ṣe midin–midin kan ti a npe ni Tirẹbọ ("Trebor") ni Apapa laipẹ yi. Ọkẹ mẹta pọnun (£60,000) ni nwọn fi silẹ lati fi kọ ile ibi iṣẹ yi lasan, koi ti kan awọn elo irin iṣẹ ti nwọn o lo nibẹ.

## O Nmu Siga

Lẹhinti nwọn ba kọ ile yi tan emi Ayiluka gbọ wipe nwọn yio gba awọn obinrin sibẹ jaburata, sugbọn ki nwọn to gba ọ, o ni lati mọ tirẹbọ na jẹ debi danimọ, o si ni lati mọ ete kun losun, o si ni lati mọ aṣ "bonfo" wọ, o si ni lati mọ ori pọn si pepa bi gele "onilegogoro."

Bi o ko ba lọkọ, o ni lati ni ikan ninu awọn abori lunlu-lẹgbẹ-ogiri ti a mọ mu ẹ lọ wo ṣinima loru ọganjọ ti ẹ si ma ku siga lala. Bi eleyi ko ba si ninu iwa rẹ ki o maṣe wahala lati wa iṣẹ wa si Apapa nitoripe aye ko ṣo fun ẹniti ko gbajumọ bi isanọ ẹlẹẹta.

## Aiyelujara

Ayiluka ni aiyelujara, awọn ọmọ Ajasẹ ni ilu Dahomey ni aiyelujara. Tani ko wa mọ wipe aiye ti lu ja ara wọn nisisiyi nigbati o le joko ninu ile rẹ l'Ọ̀rọ Baba ni Ebute Metta ki o gbe ẹrọ-nsọrọ (telephone) si okere rẹ, ki o mọ ba wọn sọrọ ni ilu Kutọnu (Cotonou) bi eniti o mba wọn sọrọ ni Yaba.

Ẹrọ isọro-si-okere (tele-link, tabi bawo ni awọn oloyinbo ti npe?) ti awọn ara ilu Dahomey yi pẹlu Ijọba Nigeria ṣeṣẹ si yi a jẹ ki ntele naa ba awọn onibara mi ara Ajaṣe sọrọ ti nno ba ni ewe taba kataba, tabi ilẹkẹ tabi aṣọ aran tabi ekisa aloku aṣọ fun tita.

Nitotọ aiye ti lu ja ara wọn sugbọn a ki gba owo Ajaṣẹ l'Eko. Bi o ba ti lowo Ọgbẹni Okotiẹbọ lọwọ ki o ma bọ lọdọ mi, ma ma ọ de ibiti a ti le ri aloku aṣọ akisa ra jamburata ni ọja Jankara.

# E ma ka Iwe Irohin Eleti–Ofe


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

PORTS ACT (CAP. 155)

NIGERIAN PORTS AUTHORITY (ELECTION) REGULATIONS 1956.

ELECTION OF MEMBERS TO REPRESENT PAYERS OF SHIPS' DUES AND PAYERS OF HARBOUR DUES, 1962.

NOTICE IS HEREBY GIVEN that in accordance with the Nigerian Ports Authority (Election) Regulation, 1956, nominations are invited for the election of Members of the Authority to represent payers of Ship's Dues and payers of Harbour Dues.

The nomination of each candidate to represent the payers of Ships' Dues shall be signed by two electors being payers of Ships' Dues, and the nomination of each candidate to represent the payers of Harbour Dues shall be signed by two electors being payers of Harbour Dues, and by the candidate in approval of his nomination.

The qualifications necessary before a Member can be elected to represent the payers of Ships' Dues or the payers of Harbour Dues, as the case may be, are enumerated in the Fifth Schedule to the Ports Act (Cap. 155) which is contained in the Schedule to the Ports (Amendment) Ordinace 1955 (No. 30 of 1955).

The names of those persons who are qualified as electors are contained in the Ships' Dues Register or the Harbour Dues Register, copies of which may be purchased from the Returning Officer at the undermentioned address at a price of 2/- each.

Nominations must be made in writing on Form A obtainable from the Returning Officer, Nigerian Ports Authority, Private Mail Bag No. 12588, Lagos, and must be delivered to him on or before the 24th day of August, 1962.

Dated this 9th day of August, 1962.

N.P.A. Notice No. 749.

BAYO KEHINDE
RETURNING OFFICER

# Ode Kan Pa Ana Re Ni Ilorin

ILORIN—Laipe yi ni ọwọ awọn ọlọpa Ijọba ibilẹ Ilorin tẹ ogbẹni ọdẹ kan ti o njẹ Lambẹ Amọsa, ẹni ogoji ọdun, ti nwọn ni o fi ibọn pa ana rẹ nigbati nwọn nṣe ọdẹ ninu igbo.

Irohin ti a gbọ ni pe Lambẹ, on ati ana rẹ Amọdu Akande lo si oko ọdẹ nibiti nwọn gbe nwọ igbo kiri, olukuluku eba ona tirẹ, ko pẹ lẹhin na ni Lambẹ yinbọn si Akande, o ṣebi eranko ni i.

Awọn Ọlọpa ko ti fi ejo ọdẹ na si kotu, nwọn si nṣe iwadi ọrọ na lọwọ.




# Dokita Elias Se Ikomojade

ẸNU kọ irohin ni ikomọkunrin ti Ọlọrun fi ta Dokita T. Ọlawale Elias ati aya rẹ lọrẹ. Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni nwọn ṣe ikomọ na ni ile wọn ti o wa ni Ọbun-Eko. Imam-Agba Liadi Ibrahim ti Mọṣalaṣi Jimọ ni o ṣe ikomọ na, nwọn si sọ ọmọ na ni Abudu Hakeemu Adeọla Akande Elias.

Ẹsẹ awọn enia gidi, awọn bi Alhaji Oloyede S. A. T. Awẹlẹnjẹ, Alhaji Y. A. Disu (Awaiyewaṣere), Alhaji-Imam J. G. B. Ọttun Z.Q., Alhaji Imam A. Ganiyu Lawal, Alhaji-Imam Amusa ti Mọsalaṣi Idoluwo, Alhaji Adamọ Durosinmi, Alhaji Ọmọ-ọba Bako, Ogbẹni Alani Shonibarẹ ati Alhaji Sogunro ni o pe ṣọṣọ sibẹ. Alhaji Ọmọ-ọba Abudu Wahaidi Elias si ha ọpọlọpọ owo fun wọn o si fi orisirisi onjẹ adidun tẹ wọn lọrun lati aarọ titi ti ilẹ ọjọ na fi ṣu.

Ki Ọlọrun da ọmọ na si ki o si ṣe e ni olori ire o.

# Egbe Ifelodun Sosi St. Jude Se Ajoyo

MUSHIN – Ni ọjọ Aje tiṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni awọn ẹgbẹ kan ti oruko wọn njẹ ẹgbẹ Ifẹloju ti Ṣọsi St. Judes ni Agọ-Ẹgba l'Ebute-Mẹtta ṣe ipade ajọyọ ninu ile ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ wọn, Ogbẹni James Ọladoyinbo Ajala ni 44, Post Office Road, Mushin. Ẹsẹ gbogbo awọn ẹgbẹ na si kun ṣọṣọ sibẹ.

Lẹhin orin ati adura, alaga ipade na, Ogbeni J. A. Adebiyi si sọ ọrọ iyanju fun gbogbo awọn ti o wa si ibi ipade ajọyọ na. Igbadun ọjọ na po, Ogbeni Ajala ati aya rẹ si fi nkan jijẹ ati nkan mimu ṣe awọn ọmọ ẹgbẹ na lalejo.

Diẹ ti aye wa lati daruko ninu awọn ti o wa si ibi ipade ajọyọ na ni: Ogbẹni M. A. Abesede (akọwe ẹgbẹ) A. Popoọla (igbakeji akọwe) A. Adeyẹmi (igbakeji alaga) Sunday, Ayannọvọ, Ọnabiyi, Adewale, Oyelọla, Lapite, Ṣowọle, Ṣoremẹkun, Adebayọ, Akiwumi, Majẹkodunmi, S. A. Balogun, Kotoyẹ, J. A. Balogun, Olusanya, Akintunde, George, Abatan, Oshinyẹmi Tanimọwo Sonọla ati Obidipẹ.

## Oke Mewa Ponun Ni Ijoba Padanu Lori Iwe Irohin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ko ba oju mu rara; nwọn si le ri aye lati ji owo gbe nibi iṣẹ na.

Alamọjuto iwe owo-nina Ijọba na tunṣe alaye pe ko si imojuto atata nibi iṣẹ na, gbogbo awọn ti ko yẹ ki nwọn gba si ibi iṣẹ na ni nwọn ko sibẹ.